# Àgbéyẹ̀wò Ìfẹ̀tọ́dunni àti Ìdájọ́ Nínú Àsàyàn Eré-onítàn Yorùbá

Àrìnpé G. Adéjùmọ̀
Department of Linguistics and African Languages
University of Ibadan
Nigeria
agadejumo@yahoo.com
&
Ọládélé Ṣàngótóyè
Department of Yoruba
School of Secondary Education
(Language Programme)
Federal College of Education
Kontagora, Niger StateNigeria
oladelesangotoye35@gmail.com

## Àsamọ̀

Ìfẹ̀tọ́dunni àti ìdájọ́ kó ipa pàtàkì nínú iṣẹ́ àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá láti ìgbà pípẹ́ wá àti títí di àkókò yìí. Bí àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí ṣe pọ̀ tó, ìwà ọ̀daràn àti ìdájọ́ kóòtù ni iṣẹ́ àwọn onímọ̀ tó ṣaajú fúnkamọ́ jùlọ láì ka àwọn ọ̀nà ìfẹ̀tọ́dunni àti oríṣìí ìdájọ́ mìíràn tó ń wáyé kún bàbàrà. Nítorí náà, a lo Ìkéde Àjọ Àgbáye àti Òfin Orílẹ̀èdè Nàìjíríà ti ọdún 1999 gẹ́gẹ́ bí àtẹ̀gùn láti ṣe àgbéyẹ̀wò ohun tí a ń pè ni ìfẹ̀tọ́dunni, ìbáṣepọ̀ àti ìdájọ́ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn àsàyàn ìwé eré onítàn méje tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ sàyàn fún àgbéyẹ̀wò. Èyí ni láti fi ìdí ìfẹ̀tọ́dunni múlẹ̀ àti ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin afẹ̀tọ́dunni àti ẹni tí a fẹ̀tọ́ dùn nípasẹ̀ ìṣẹ̀dáǹiyàn, ọjọ́ orí, ẹ̀sìn, ipò àti àwọn ọ̀nà ìdájọ́. Àwọn ìwé náà ni: Akínwùmí Ìṣọ̀lá (1970) *Ẹfúnṣetán Aníwúrà,* TAA Ládélé (1971) *Ìgbà Ló De,* Adébáyọ̀ Fálétí (1972) *Baṣọ̀run Gáà,* (1980) *Wọ́n rò pé wèrè ni,* Láwuyì Ògúnníran (1977) *Ààrẹ-Àgò Aríkúyẹrí* , Adéṣọlá Ọlátẹ́jú (2009) *Iná Ràn* àti Agboọlá Àyándìran (2016) *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀.* Tíọ́rì Máàsì to níí ṣe pẹ̀lú ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ni a fi ṣe òsùnwọ̀n nítorí pé ohun gbogbo tí ó ṣẹlẹ̀ nínú àwọn ìwé náà jẹ mọ ìjẹgàba, ìrẹ́nijẹ, ìjàfẹ́tọ̀ọ́ ẹni. Ìwádìí fi hàn pé afẹ́ ayé, ìṣèlú, ọrọ̀ ajé àti ìsinúbí ní ó jẹ́ okùnfa ìjẹgàba èyí ti

ó sì yọrí sì ìpànìyàn, ìbínú-òdì, ìfiniṣètùtù ọla, ìjínigbégbowó, ìfiyàjẹọmọdé, ìfọmọsòwò, ìmúnitìmọ́lé lọ́nà àìtọ́, ìfiniṣerú àti ìfipámúnisìn Àwọn ẹ̀tọ́ mìíràn tí wọn tún tẹ̀ lójú ni ẹ̀tọ́ ìwàláàyè, òmìnira ìdágbé, ìyì ọmọnìyàn, ìyanfanda àti ìkórajọ. Àbájáde ìwádìí láti inú àwọn ìwé eré onítàn tí a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí fi yé wa pé ìfẹ̀tọ́dunni kò ní ṣe pẹ̀lú ẹ̀dánìyàn tàbí ẹ̀sìn ẹni tí wọ́n tẹ ẹ̀tọ́ rẹ̀ lójú. Ìdájọ́ oríṣìí mẹ́ta to farahàn nínú iṣẹ́ yìí ni ìdájọ́ kóòtù, ìdájọ́ lọ́nà ìbílẹ̀ àti ìdájọ́ tìpátìkúùkù- mímú òfin lò lọ́wọ́ ara ẹni. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé ọ̀rọ̀ ìfẹ̀tọ́dunni àti ìdájọ́ kò jẹ àjèjì ni àwùjọ Yorùbá, o ti wà nínú àṣà Yorùbá kí àwọn oyinbo tóó gòkè. Ìfẹ̀tọ́dunni ti a kò ba tètè mójútó le ṣe okùnfà òmíràn tí ó burú ju tàkọ́kọ́ lọ, ṣùgbọ́n ìdájó tìpátìkúùkù kò dára. Ìlànà ìbílẹ̀ àti òfin ló dára jùlọ láti jà fún ẹ̀tọ́ ẹni.

## Ìfáárà

Ọ̀kan pàtàkì lará ogun tí ó ń bá àwùjọ àgbáyé fínra lẹ́nu lọ́ọ̀lọ́ọ̀ yìí ni ogun ìfẹ̀tọ́-ẹni-dunni àti ìjẹgàba-lórí-ẹni. Onírúurú akitiyan sì ni àwọn lẹ́gbẹ́lẹ́gbẹ́, lọ́gbàlọ́gbà ń ṣe láti rí i pé ogun yìí di àsẹ́wọlẹ̀. Akitiyan àwọn Ẹgbẹ́ Ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn lórí títán ìṣòro yìí kò kéré. Wàhálà àti ìdààmú tí ìfẹ̀tọ́-ọmọnìyàn dunni ń ko ba àwùjọ sí jẹ́ ohun tí àwọn oníṣẹ́-ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ káàkiri àgbáyé ń ṣàfihàn nínú iṣẹ́ ọnà wọn. Nínú àpilẹ̀kọ yìí, a óò ṣe àmúlò tíọ́rì fífi ojú ìbágbépọ̀ wo lítíréṣọ̀ láti ṣàfihàn bi ìwà títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú ṣe jẹyọ nínú àṣàyàn eré onítàn méje. Eré onítàn tí a mọ̀-ọ́n-mọ ṣàyàn fún iṣẹ́ yìí ni Akínwùmí Ìṣọ̀lá (1970) *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, TAA Ládélé (1971) *Ìgbà Ló De,* Adébáyọ̀ Fálétí (1972) *Baṣọ̀run Gáà* àti (1980) *Wọ́n rò pé wèrè ni*, Láwuyì Ògúnníran (1977) *Àárẹ-Agọ̀ Aríkúyẹrí,* Adéṣọlá Ọlátẹ́jú (2009) *Iná Ràn* àti Agboọlá Àyándíran (2016) *Àárò Wọ̀rọ̀kọ̀.*

Abala Tíọ́rì Máàsì èyí tó jẹ mọ fífi ojú ìbágbépọ̀ ẹ̀dá wo iṣẹ́ ọ̀nà ni yóò jẹ awòjíjí láti wo àwọn ìsẹ̀lẹ̀ tó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ èyí tí àwọn òǹkọ̀wé fẹ́ kí ó di mímọ̀. Ohun tí tíọ́rì yìí ń tẹnumọ́ ni pé kí á tó le gbẹ́ iṣẹ́ kan jinlẹ̀, a níláti wo àwùjọ tí iṣẹ́ náà ti wáyé nítorí pé ipa pàtàkì ni àwùjọ ní lórí iṣẹ́ àtinúdá kan. Tíọ́rì yìí gbà pé àwùjọ ló ni èdè tí òǹkọ̀wé lò, orí ènìyàn àwùjọ ni iṣẹ́ náà dá lé lórí, àṣà àwùjọ kò le sàì farahàn nínú iṣẹ́ àtinúdá, òǹkọ̀wé papàá jẹ́ ara àwùjọ, ìsẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló kọ nǹkan lé, o sì ṣe é láti kọ́ àwùjọ lọ́gbọ́n ni. Èrò Ògúnṣínà (2006:7-8) ni pé gbogbo ààlọ́ àti ààlọ̀ iṣẹ́ òǹkọ̀wé, orí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló dá lé. Àwùjọ ló ni gbogbo èròjà tí òǹkọ̀wé lò àti pé iṣẹ́ náà wà fún àǹfàání àwùjọ ni.

A wo bi àwọn òǹkọ̀wé wọ̀nyí ṣe ya àwòrán ìfẹ̀tọ́dunni nínú ìkọlura àjọṣe láàrín ẹ̀dá ènìyàn àti ìdájọ́ tí ó tẹ̀lé e. Iṣẹ́ yìí walẹ̀jìn nípa fífi ẹ̀tọ́ ará ìlú hàn wọ́n ni ìbámu pẹ̀lú ìlànà tí Àjọ Àgbáyé gbé kalẹ̀ lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyan, èyí tó ràn wọ́n lọ́wọ́ láti mọ ẹ̀tọ́ ti ẹnìkan le tẹ̀ lójú mọ́lẹ̀ ní pàtó. Iṣẹ́ yìí ṣàlàyé ìjẹyọ ìfẹ̀tọ́ ẹni-dunni nínú àwọn eré onítàn tí a yẹ̀wò, okùnfà rẹ̀, ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin afẹ̀tọ́dun-ni àti ẹni tí a fẹ̀tọ́ dùn, ìdájọ́ tó wáyé àti bí a ṣe le mú àdínkù ba ìwà

yìí. Nínú iṣẹ́ yìí a yiiri ọ̀ná tí a gbà yanjú ìṣòro ìfẹ̀tọ́-ẹni-dunni nínú àwọn eré onítàn náà wo, pẹ̀lú èrò pe àwùjọ lápapọ̀ le ṣe àwòta àwọn ọ̀nà yìí, kí wọn sì ṣe àmúlò wọn ni òde-òní, kí ọ̀rọ̀ ìfẹ̀tọ́-ẹni-dunni lè di àfiṣẹ̀yin ti eégún ń fi aṣọ. Àtubọ̀tán èyí sì ni pé ìdágbàsòkè púpọ̀ ni yóò dé ba àwùjọ.

## Ohun tí Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn Jẹ́

Kò sí àníàní pé àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ lórí ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ẹ̀tọ́ ọmọnìyan, ìwà ìjẹgàba lórí ẹni tàbí ọ̀nà ti àwọn ẹ̀dá mìíràn ń gbà rẹ ẹnìkejì wọn jẹ àti ìdájọ tí ó tẹ̀lé e. Adégbìtẹ́ (2014:1) túmọ̀ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn bí àwọn ohun tó tọ́ si ẹ̀dá ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ìlànà òfin ìjọba ṣe là á kalẹ̀. Kì í ṣe ohun tí a ń bẹ̀bẹ̀ fún: *"An entitlement of every person which is sanctioned by law and enforceable against everyone. They are the rights that belong to all human beings and citizens of a country."*Akínyẹmí (2002:2) náà gbà pé àbímọ̀ ènìyàn ni ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́. Kì í ṣe ẹ̀bùn tí a fún ni, fún ìdí èyí a kò le gbà á padà lọ́wọ́ ẹni. Ìdí nìyí tí ó fi sọ pé *"Rights are inherent in the nature of man. Man is born with rights. It is not a gift from a government to be given as a reward for good behaviour or withheld or withdrawn for bad behavior."* Adéyẹmí (2019:16) ni tirẹ̀ so ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn mọ́ òfin orílẹ̀ èdè ẹni àti ẹ̀tọ́ ẹni gẹ́gẹ́ bi ẹni tó ń gbé ni orílẹ̀ èdè tàbí àwùjọ kan. O gbà pé ojúṣe ìjọba ni láti rí i pé a kò fi ẹ̀tọ́ ẹnìkọ̀ọ̀kan dùn ún, kí ó sì ṣàlàyé ibi tí ẹ̀tọ́ náà mọ fún wọn. O ní *"Human rights are said to be those prerogatives, priviledges and freedom which a citizen can legitimately enjoy by virtue of his status of citizenship. It is the constitutional responsibility of the state to guarantee these rights and determine their limitations.*

Èrò Chiroma (2010:31) kò yàtọ̀ sí ti òkè yìí. Òun náà gbà pé gbogbo ènìyàn láwùjọ ni ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn tọ́ sí. Èrò yìí ló gbé kalẹ̀ báyìí pé.

> *Rights means that to which a person has a just and valid claim…. Human pertains of having characteristics of the nature of mankind. Human rights are thus rights which all person everywhere, and at all times have by virtue to being mortal and rational creative.*
> (Ẹ̀tọ́ jẹ́ ohun tí ó tọ̀nà tí ènìyàn sì lè béèrè fún…. Ẹni tí ó ni àbùdá ọmọnìyàn. Ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́ àwọn ẹ̀tọ́ tí gbogbo ènìyàn níbi gbogbo, nígbà gbogbo nítorí wọn jẹ abẹ̀mí àti ẹni tí ó lè ronú.)

O hàn gbangba nínú àwọn oríkì tí àwọn onímọ̀ gbékalẹ̀ lókè yìí pé ọ̀rọ̀ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́ ohun ti gbogbo àgbáyé mú ni ọ̀kúnkúndùn. Èyí ló fàá tí ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè ṣe máa ń hun-un mọ́ òfin orílẹ̀-èdè wọn. Bí àpẹẹrẹ, ìlàkalẹ̀ òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lágbàáyé jẹ́ ààringbùngbùn fún ohun tí òfin orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ti ọdún 1999 dúró lé lórí. Àrífayọ̀ mìíràn tí a tún rí nínú àwọn àlàyé òkè wọ̀nyí ní pé ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́ àǹfààní tí Ẹlẹ́dàá pèsè fún ẹ̀dá ènìyàn láti lò láì gbọdọ̀

sí alátakò. Ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn jẹ́ ohun tí gbogbo ọmọ ìlú gbọ́dọ̀ ni ẹ̀tọ́ sí lái fi ti ẹ̀yà, ẹ̀sìn, ìṣẹ̀dánìyàn tàbí èdè ṣe. Ó jẹ́ àwọn ìlànà tí ìjọba là kalẹ̀ fún ìbágbépọ̀ àlàáfíà láàrín àwùjọ lái rẹ ẹnìkankan jẹ tàbí fi ẹ̀tọ́ ẹnikẹ́ni dùn un.

Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá ka ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn sí nǹkan bàbàrà. Àwọn ìwé ẹ̀sìn lọ́kan-ò-jọ̀kan náà ń tọ́kasí ìṣepàtàkì ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Bí àpẹẹrẹ nínú Bíbélì tíí ṣe ìwé ìlànà ẹ̀sìn àwọn ọmọlẹ́yìn Kristi, Ọlọ́run ka ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn sí. Nínú òfin mẹ́wàá tí Ọlọ́run fún Mósè gẹ́gẹ́ bí Bíbélì Mímọ́ ti ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀ nínú Ekisodu 20:1-17, mẹ́rin péré nínú òfin náà ló níí ṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, nígbà tí mẹ́fà yòókù jẹ èyí tí ó wà fún ìdánmọ́rán ìbágbépọ̀ láàrin ẹ̀dá ènìyàn. Síwájú síi, nínú Bíbélì kan náà, Ọlọ́run pa á láṣẹ fún àwọn ọmọ Isírẹ́lì pé:

> Ìwọ kò gbọdọ̀ rẹ ẹnìkejì rẹ jẹ, bẹ́ẹ̀ni ìwọ ko gbọdọ̀ gba owó àìtọ́. Owó ọ̀yà alágbàṣe kò gbọdọ̀ sun ọ̀dọ̀ rẹ títí di òwúrọ̀. Ìwọ kò gbọdọ̀ bú adití tàbí fi ohun ìdìgbòlù síwájú afọ́jú. Ẹ̀yin kò gbọdọ̀ ṣe àìsòdodo ni ìdájọ́, ìwọ kò gbọdọ̀ gbe tálákà, bẹ́ẹ̀ni o kò gbọdọ̀ ṣe ojúsàájú alágbára, ní òdodo ni ki o máa ṣe ìdájọ́ ẹnìkejì rẹ. (*Bíbélì Mímọ́*: Lefitiku 19:13-15).

Àgbéyẹ̀wò ìlànà wọ̀nyí ti Ọlọ́run fún Mósè láti máa fi darí àwọn ọmọ Ísírẹ́lì yìí wúlò títí di òní nítorí ohun ló pilẹ̀ ètò ìdájọ́ òfin ìgbàlódé tí a ń lò ni kóòtù. Àyẹ̀wò àwọn ìlànà yìí sàfihàn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn mẹ́ta (i) Ẹ̀tọ́ si àìfọwọ́ọlágbánilójú (ii) Ẹ̀tọ́ si gbígba owó ọ̀yà iṣẹ́ ti a ṣe àti (iii) ẹ̀tọ́ sí ìdájọ́ òdodo.

Ó ṣe pàtàkì láti mẹ́nu bà á pé títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú ni okùnfa aáwọ̀ àti ìdájọ́. Bí ẹnìkan ba sàdeédé tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀, tí ó fẹ́ rẹ́ onítọ̀hún jẹ, tí ìyẹn kò sì fẹ́ gbà ní ojúbọ̀rọ̀, èyí lè jẹ orísun wàhálà. Kíkọ̀ tí ẹni tí a fẹ́ rẹ́ jẹ bá kọ̀ le bí aáwọ̀, ìfẹ̀hónúhàn, ìfẹ̀hónúhàn le bí rògbòdìyàn, èyí le tún bi títẹ ẹ̀tọ́ ẹni tó ń rẹ́nijẹ lójú, ti ìtẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú yóò sì máa ràn mọ̀-ọ̀n bí iná ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn.

Raimi (1990) ṣe àgbéyẹ̀wò onírúurú ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ń gbà tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọlẹ̀ láwùjọ Yorùbá. Lára irú ẹ̀tọ́ bẹ́ẹ̀ ni ki ẹ̀gbọ́n gbẹ́sẹ̀ le ogún tó jẹ́ ti tẹ̀gbọ́n tàbúrò, kí ẹnìkan ta ilẹ̀ kan fún ènìyàn méjì tàbí mẹ́ta, kí agbanisíṣẹ́ má sanwó ọ̀yà fún òsìsé àti àwọn ọ̀nà mìíràn ti wọn ń gbà fi ẹ̀tọ́ dunni. O tọ́kasí àwọn ọ̀nà tí a fi le jà fún ẹ̀tọ́ ẹni lái lọ sí kóòtù tàbí hùwà jàgídíjagan, bíi lílọ fi ẹjọ́ sùn lórí ètò *"Ṣó dáa bẹ́ẹ̀"* tí ó máa ń wáyé lórí Rédíò Ìjọba Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ (Radio Ọ̀yọ́). Adéjùmọ̀ (2019:13) náà tọ́kasí pé àwọn akéwì láwùjọ Yorùbá máa ń fi ewì wọn sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, wọn a sì máa tako títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú nínú ewì wọn lójúkojú láti ìgbà ìwàṣẹ̀. Kódà lóde òní wọn a máa lo ewì àpilẹ̀kọ àti àwo rẹ́kọ́dù tí wọ́n tẹ jáde láti tàbùkù títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú.

## Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn Láwùjọ Yorùbá

Ọ̀rọ̀ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn kìí ṣe àjòjì láwùjọ Yorùbá. Èròngbà Anyaẹgbunam (2014:104) ni pé àwọn Yorùbá kò ni nǹkan tó ń jẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn títí tí àwọn òyìnbó aṣèjọba amúnisìn fi dé tí wọn sí gbé ìlò òfin alákọsílẹ̀ dé. Àkíyèsí àwọn onímọ̀ tako èrò yìí. Raimi (1990), bákan náà Adéjùmọ̀ (2019) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀rọ̀ ìtẹ̀tọ́ẹni lójú àti ìjà fún ètọ́ ọmọnìyàn kì í ṣe àjòjì nílẹ̀ Yorùbá. Èyí fihàn pé kí àgbàdo àgbékalẹ̀ òfin Òyìnbó tó dé sí àwùjọ Yorùbá, nǹkan kan ni adìẹ wọn ń jẹ. Kí àwọn Òyìnbó tóó dé si ààrin Yorùbá ni wọn ti ń ṣe àmúlò òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn nínú àṣà wọn, o kàn jẹ pé kò sí ní àkọsílẹ̀ bi ìlànà ti àwọn olóyìnbó ni. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn Yorùbá kò ni àkọ́sílẹ̀ òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn saájú ìmúnisìn, àwọn ẹ̀rí láti inú òwe, àlọ́ onítàn, àṣàmọ̀ àti ètò ìdájọ́ wọn fi hàn pé Yorùbá mọ ohun tó ń jẹ́ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, wọn sì lòdì sí títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí a ba wo àwọn òwe inú àte ìsàlẹ̀ yìí, a óò ríi pé èrò Yorùbá wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní ìlànà òfin.

| | Òwe Yorùbá | Òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lóde òní |
|---|---|---|
| 1.<br>2. | Ọmọ kì í pa ọmọ jaye.<br>Ọ̀gẹ̀dẹ̀ dúdú kò yá bùsán, ọmọ burukú kò yá lùpa. | Right to life. |
| 3.<br>4. | Àìlè ṣọ̀rọ̀ ni ìbẹ̀rẹ̀ orí burúkú.<br>Ọba kì í mu ọ̀kọrin. | Right to freedom of expression |
| 5.<br>6. | Kì í jẹ ti baba tọmọ, kó má nìí ààlà.<br>Bí ọmọdé ba tóó lọ́kọ́, a lọ́kọ́. | Right to private family life. |
| 7.<br>8. | Òjò òwúrọ̀ tíí bi olówó nínú, olówó gẹlẹtẹ, ìwọ̀fà náà gẹlẹtẹ.<br>Olówó ẹni kìí rorò kó wí pé kí á má su. | Right to human dignity |
| 9.<br>10. | Àgbà ṣe pẹ̀lẹ́, ọmọdé ń bọ̀ wá dàgbà.<br>Ẹyin ló ń dàkùkọ | Child rights act. |
| 11.<br>12. | Ẹ̀sìn kò fàjà, Ọlọ́run ló mẹni tó ń sin òun.<br>Tọwọ́ ọmọ làá gbà ẹnìkan kò le gba tinú ọmọ. | Right to freedom of thought, conscience and religion. |

Ohun tí a fẹ́ mu jáde láti inú àpẹẹrẹ wọ̀nyí ni pé kò sí èyíkéyìí nínú ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn méjìdínlógún (18) ti àkọsílẹ̀ Àjọ Àgbáyé (UNO) fọwọ́ sí tíí ṣe *Universal Declaration of Human Rights* tí Yorùbá kò ni òwe tàbí àsàyàn ọ̀rọ̀ tí ó dọ́gba pẹ̀lú rẹ̀. Èyí fi hàn pé láti ọjọ́ tí aláyé ti dáyé ni ìfarahàn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ti wà nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá.

## Àfihàn Ìfẹ̀tọ́duni àti Ìdájọ́ nínú Àsàyàn Eré Onítàn Yorùbá

Gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú afigège jà fún ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, ọ̀pọ̀ òǹkọ̀wé eré onítàn ni wọ́n ti fi gègé tú àṣírí ìwà ìrẹ́nijẹ àti ìfọwọ́ọlá-gbá-ni-lójú ní àwùjọ wa. Ògúnníran (1977) *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí* fi Ògúnrìndé Ajé hàn gẹ́gẹ́ bí jagunjagun tí ó ti ja àjàṣẹ́gun ni ọ̀pọ̀ ogun ìta ṣùgbọ́n ti ogun ilé borí rẹ̀ nítorí inúfùfù àti àìfarabalẹ̀ rẹ̀. Lọ́jọ́ ti Ògúnrìndé Ajé ń bọrí rẹ̀ látàrí àwọn àṣeyege tí ó ti ṣe, tí àwọn ìyàwó rẹ̀ ń kì í ni mẹ́sàn-án-mẹ́wàá ni wàhálà wọlé tọ̀ ọ́, tí ogun ilé sì borí rẹ (10-19). Ọmọ rẹ̀ méta tó wọ́kú lọ́jọ́ náà mú kí inú rẹ̀ bàjẹ́, inú bí i, ó sìwàhù nípa títa ìyàwó rẹ̀ tí wọn fi ẹ̀sùn kàn pé òun ló ṣe okùnfà ikú wọn lọ́fà, tí ìyẹn sì gbabẹ̀ kú (1-29). Lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn ni ó tó yé e pé Ìyáálé òun Aṣiyanbí ló fi owú jíjẹ parọ́ mọ́ Fátọ̀lá nítorí pé o gbayì jù àwọn méjì yòókù-Asiyanbí àti Adépèlé lọ ni ojú agbo. Ọ̀rọ̀ náà di wàhálà, ó di arukusu. Lásìkò ìgbẹ́jọ́, ní kọ̀bì Basọ̀run Ògúnmọ̀lá, Asiyanbí ṣàlàyé pé ọkọ àwọn Ogunnde Ajé ló gbin èbù wàhálà sínú ìdílé nípa yíyan ààyò àti ìpọ̀sin lójú agbo ni àsìko ti àwọn ń sun rárà fún ún lọ́jọ́ tó ń bọri rẹ̀. (Lọ́jọ́ náà ló yin Fátọ̀lá, tí ó sì dójúti Adépèlé àti Aṣiyanbí (18-19). Aṣiyanbí jẹ́ kí ìgbìmọ̀ ìgbẹ́jọ́ mọ̀ pé ọkọ àwọn ló forí àwọn gba ara wọn. (72)

***Aṣiyanbí:*** A kuku fẹ́ràn ara wa dáadáa tẹ́lẹ̀. Baba wa náà ló ba gbogbo rẹ̀ jẹ́. Oun lo mo igi tẹ́ẹ́rẹ́ tó yẹnú igbó, òun ló mọ òsùmàrè tó yẹ ojú ọ̀run. Òun ló mobìnrin tẹ́ẹ́rẹ́ tó yẹ ọkọ lọ́jọ́ ijó… òun ló pogun tó rógun, òun ló pọ̀ràn tó rọ́ràn; òun lo jókòó tó rọ̀gbọ̀kú tán tí ń tọ́ láaróyè lójú òde. Òun ló ń forí wa gbára wa. Aà jà, a-à ta ọ̀rẹ́ ni wá (Ògúnníran, 1977:55).

Lẹ́yìn ìwádìí fínnífínní si okùnfà ìpànìyàn tó wáyé náà, Baṣọ̀run Ògúnmọ̀lá gbé ìdájọ́ kalẹ̀:

***Baṣọ̀run:*** Èmi ni Òdùmarè kó gbogbo èèyàn ìlú yìí le lọ́wọ́ Nílé lóko àti ni Ìdálẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni bí ẹ̀mí ọ̀kan ba sì bọ́ láìtọ́, èmi ni ń o rojọ́ rẹ nídènà ọ̀run. Nítorí náà mo dá ọ (Ògúnrìndé Ajé) lẹ́bi pé o gba ẹ̀mí Fátọ̀lá láìtọ́, a ó sì gba tìrẹ náà díi. Àṣẹ mi nù-un (Ògúnníran 1977:104).

Tíọ́rì Máàsì fi ara hàn níbí pé àwọn Ọlọ́lá (Ògúnrìndé Ajé) a máa rẹ́ mẹ̀kúnnù jẹ. Ipò ọlá ti Ògúnrìndé Ajé wà ló fi rẹ́ Fátọ̀lá jẹ nípa bí ó ṣe pa á láì ṣe ìwádìí ìjìnlẹ̀ sí ẹ̀sùn ti ìpànìyàn tí wọ́n fi kàn án.

Nínú *Baṣọ̀run Gáà*, ó ṣẹlẹ̀ pé Baṣọ̀run Gáà gba ẹ̀mí Àgbọ́nyìn (Ọmọ Ọbabìnrin) lọ́nà àìtọ́, ó ní kí Babaláwo òun fi bá òun ṣètùtù ọlà. Bí a bá wo ohun tó rọ̀ mọ́ ikú Àgbọ́nyìn jìnlẹ̀ a ó rí ì pé owú jíjẹ àti ẹ̀mí ìkórìíra ló mú Baṣọ̀run Gáà hu ìwà tó hù. Àkọ́kọ́ ni pé, ó gbọ́ pé Aláàfin Abíọ́dún ń sọ fún ìyá Mọdẹ pé bí òun bá gbésẹ̀, ọmọ òun Àgbọ́nyìn ni kí wọn mú jọba – (58) èyí ti kò dùn mọ́ ọn nínú pé ipò ìjòyè ni òun yóò máa wà títí, òun kò le di ọba, yàtọ̀ sí èyí, inú rẹ̀ kò dùn pé wọ́n ń ronú àti fi obìnrin jẹ Aláàfin ó ní:

**_Gáà:_** Gbàgi! Ẹ lọ í lò ó (Àgbọ̀nyìn bẹ̀rẹ̀sí ké, wọ́n gbé e jáde)
Mo dúpẹ́! Òun náà ló rán mi létí
Àgbọ́nyìn! Mo dúpẹ́
Mo ségun ọ̀ta mi
Nígbà tó bá kú tán
Kí wọn ó lọ sínú igbó
Kí wọn ó mágbọ̀nrín míì fi jọba (Fálétí, 1972:99).

Bí a bá fi ojú èrò Ìsọ̀lá nínú *'Ìhónú ẹlẹ́wù ẹtù'* Ìsọ̀lá (1991:29-37) wo ìṣẹ̀lẹ̀ yìí a ó ri pé àwọn ẹlẹ́wù ẹtù méjì a máa dojúkọ ara wọn nítorí ojú àmúwayé wọn lórí nǹkankan àti àkàsí àwùjọ le yàtọ̀ síra. Èyí túmọ̀ sí pé ojúwò àti ojú àmúwayé le satọ́kùn ìfẹ̀tọ́dunni. Baṣọ̀run gbà pé àwùjọ ń fẹ̀tọ́ rẹ dùn un nípa pé kò le jọba (49) ìdí nìyí tí ó fi fẹ̀tọ́ ìwàláàyè dun Àgbọ́nyìn. Yàtọ̀ si ẹ̀tọ́ ìwàláàyè, ọ̀pọ̀ akopa ní àwọn alágbára tẹ̀ lójú mọ́lẹ̀, (Òbe bẹ aláàárù lórí láìsẹ̀), Gáà kò jẹ́ kí wọn bá a wí, ẹ̀tọ́ mìíràn tí Gáà tún tẹ̀ lójú mọ́lẹ̀ ni ti fífi ènìyàn si àhámọ́ lọ́nà àìtọ́. Gáà Ọ̀ṣọ̀run pàsẹ fún Gbàgì ẹrú rẹ láti mu Sàmù (àgbà ìjòyè) si àhámọ́ kí o sì dana ata wẹẹrẹ sínú yàrà náà.

**_Gáà:_** Gbàgi, mú un (Sàmù) lọ si yàrá ọ̀kánkán nnì, kẹ́ẹ tìí mọ́bẹ̀, kóo fata wẹẹrẹ síi, kó o dáná sí ì, kójù rẹ̀ o pọn díẹ̀ (Fálétí, 1972:91).

Níkẹyìn ikú ẹ̀sín ni Baṣọ̀run Gáà tí ó tẹ ẹ̀tọ́ ìwàláàyè Àgbọ́nyìn lójú mọ́lẹ̀ kú. Ọba Abíọ́dún pàṣẹ pé kí wọn rì í mọ́lẹ̀ láàyè sí Ọjà Akẹ̀sán kí ẹnìkọ̀ọ̀kan máa lọ gé ẹran ara rẹ̀ dànù lékìrílékìrí. Ikú gbígbóná ló pa Òbé àti Ọláyìíòtán tí wọn jẹ ayé alábátà lásìkò tí ogun Ọyalabí (Àárẹ-Ọ̀nà-Kakaǹfò) jẹ ilé Gáà run.

Bákàn náà, nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, a rí àpẹẹrẹ bí ìyálóde Ẹfúnṣetán ṣe ń rẹ àwọn ẹrú rẹ̀ jẹ tí ó ń fi wọ́n dá àrà tí ó wù ú. Kò sí àríyànjiyàn pé níní ẹrú wà nínú àṣà Yorùbá, ṣùgbọ́n wọn kò dunnú si lílo ẹrú nílòkúlo. Nínú àsàyàn ọ̀rọ̀ wọn, wọn máa n sọ pé *"ẹrú ní baba, ọ̀nà ló jìn"*. Nígbà tí agbára ń gun Ìyálóde Ẹfúnṣetán o ni:

***Ìyálóde:*** Gbogbo ẹrú tí mo bá fowó mi rà, ó dájú wọn kò kúkú gbọdọ̀ bímọ. Èyí tí ó bá lóyún nínú àwọn omidan ọ̀run alákeji ni yóò ti bí i. Ẹrúkùnrin mi tí ó bá sì fẹ́yàwó, ànàbẹ́rí bi ajá ògún sógán! Bẹ́ẹ̀ ni! Ṣé mo ti ń kọ́ wọn lọ́gbọ́n ti pẹ́. Ní ì-dunta, ọmọge mẹ́tàlá ló lọ láìròtẹ́lẹ̀, ọkùnrin méjìdínlọ́gbọ̀n ló lọ sájò àrèmabọ̀ bẹ́ẹ̀ ni, èmi Ẹfúnṣetán kò gba gbẹ̀rẹ́! (Ìṣọ̀lá 1970:9)

Lára àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn tí tẹ̀ lójú nínú ayé àwọn ẹrú rẹ̀ ni (a) Ẹ̀tọ́ ìyì ì-jénìyàn (Right to dignity of human person), (b) Ẹ̀tọ́ ìwàláàyè (Right to life) àti (d) Òmìnira lọ́wọ́ ìfìyàjẹnu (Freedom form torture or degrading punishment). Ìyálóde tẹ ẹ̀tọ̀ Iyì Ìjẹ́nìyàn lójú nípa fífi ebi pa àwọn ẹrú rẹ̀, ó so wọ́n mọ́lẹ̀ bí ẹran, kò fún wọn lóore ọ̀fẹ́ láti ṣe abiyamọ. Ọ̀kan nínú àwọn ẹrú rẹ̀ tó ń jẹ́ Ìtáwuyì ni:

**Ìtáwuyì:** Báwo ni inú mi ṣe le dùn lórí ìyà
Àwa tí ó so mọ́lẹ̀ bi ẹran ńkọ́?
Ṣe nǹkan re ni kí wọn máa so ọmọ ènìyàn mọ́lẹ̀? (Ìsọ̀lá 1970:19).

Síwájú síi, ìyálóde tẹ ẹ̀tọ́ sí àìpọ́nilójú àti àìfìyàjẹni (freedom from torture and degrading punishment), àti ẹ̀tọ́ sí ìwàláàyè Ògúnjìnmí mọ́lẹ̀ nípa bí ó ṣe pàsẹ pé kí àwọn ẹrú rẹ̀ fìyà jẹ ẹ́ látàrí ẹ̀sùn èké tí wọn fi kàn an pé ó jí ọ̀pẹ Ìyálóde kọ. Látínwọ́ sọ pé òun ni òun bẹ Ògúnjìnmí ní ọ̀pẹ kọ ni ààlà oko òun àti ti Ìyálóde, kìí ṣe pé ó jalè ni oko Ìyálóde. Níbi tí àwọn ẹrú Ìyálóde ti ń lù ú nílùkulù ni ó ti kú mọ́ wọn lọ́wọ́. Ògúnníyì ni:

**Ògúnníyì:** Ṣe gbogbo wa ni a gbọ́ pé àwọn ẹrú Ìyálóde lu akọ̀pẹ kan pa loko? Mo gbọ́ pé wọ́n ti fẹ́ pa ọ̀rọ̀ náà mọ́lẹ̀, wọ́n fẹ́ fi ẹsẹ̀ ilé tọ̀ ọ́. Ẹ̀rù ń ba àwọn ìjòyè láti kojú Ìyálóde (Ìṣọla 1970:34).

Yàtọ̀ sí pé Ìyálóde fi ẹnu ara rẹ̀ jẹ́wọ́ pé ìpakúpa ni òun máa n pa ẹrú tí ó bá tàpá sí òfin òun, ìlùkulù ni ó máa ń lù wọn. Ó pàsẹ pé kí abẹ́nilórí bẹ́ orí ẹrúbìnrin rẹ̀ tó ń jẹ́ Adétutù nítorí pé ó lóyún. Ìyálóde ni:

**Ìyálóde:** Ẹ súnmọ́ bí, ọmọ tí kò bá gbọ́n
Ìyà àjẹbólórí ni yóò kọ́ ọ
Na ọwọ́ rẹ síbí, ẹni-ìyà, òkú ìgbẹ́
Èmi ni ng ó pa yín

Kíni ẹ fi mí pè? (Ìsọ̀lá 1970:5).

Gbogbo ìwà títẹ ẹ̀tọ́ tẹrútọmọ lójú mọ́lẹ̀ tí Ẹfúnṣetán Aníwúrà hù yìí ló sokùnfà bí Látòósà ṣe jíròrò pẹ̀lú àwọn ìgbìmọ̀ ìlú tí wọn sì pinnu láti jẹ ilé rẹ̀ run. Lára kókó tí a rí fàyọ níbí ni pé àwọn ọlọ́lá, a máa gbógun ti ara wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n a sì máa tẹ ẹ̀tọ́ ara wọn lójú lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan fún àwọn ìdí kan bí ọ̀rọ̀ bá dójú rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ ọrọ̀ ajé lokùnfa ìfẹ̀tọ́duni nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Lásìkò tí Ẹfúnṣetán wà ní ìgbèkùn Látòósà ni ó banújẹ́, ó gbé májèlé jẹ, ó sì kú. Bákan náà ni a rí ipé ìyànjú àti faṣẹ̀ ọba múlẹ̀ kí wọ́n sì fi agbára ọba láwùjọ múlẹ̀ ló fa fífi Ẹfúnṣetan sí ìgbèkùn.

Nínú eré onítàn *Iná Ràn*, a rí àpẹẹrẹ ibi tí àwọn akọ́dà, agbowó orí ti ń fìyà jẹ àwọn 'arúfin' (àwọn tí kò san owó orí) lọ́nà àìtọ́. Bí àpẹẹrẹ a rí ibi tí Yésúfù àti Àmùdá (àwọn agbowó orí) ti ní kí wọn máa fò bí ọ̀pọ̀lọ́, tí wọn sì ń kọ orin àbùkù fún wọn, orin *"Elétí ehoro Gbọ̀n-ń-sẹ́ńsẹ́"* ni wọ́n ń kọ fún wọn. Yàtọ̀ sí èyí, ńṣe ni wọn ń mú wọn fi tipátipá fò bí ọ̀pọ̀lọ́ (52).

Nínú eré onítàn yìí kan naá àpẹẹrẹ títẹ ẹ̀tọ́ ìwàláàyè ẹni lójú pọ jàǹtìrẹrẹ. Bí àpẹẹrẹ, nítorí pé Làmídì kò san owó orí àwọn àgbowó orí lu ú pa.

**Àmùdá:** O fẹ́ẹ̀ máa díbọ́n? O jẹ́ dìde ká tó fi lílù dárà sí ẹ lára. (Àlàyé) Ó ti rẹ Làmídì, ó bẹ̀rẹ̀sí mí họ̀ọ̀, kò le dìde mọ. Àwọn akọ́dà kó ìbóǹbó tì í, ó sì dákú mọ́ wọn lọ́wọ́. Àwọn akọ́dà yọ́ pọ́rọ́, wọ́n sá lọ. Àwọn arúfin yòókù pé Làmídi títí ṣùgbọ́n kò jí mọ́ (Ọlátẹ́jú 2009:52-53)

Ìbínú lílù tí wọ́n lu Làmìdí pa yìí lo mú Àwọn ará ìlú Ọ̀bọdà kọjú oro sí wọn, bí wọn ti ń pa Akọ́dà ni wọ́n ń ba ọlọ́pàá jà. Ọ̀kan nínú àwọn arúfin ni:

***Arúfin kìn-ín-ní:*** Ó tó gẹ́ẹ́. Alubàtá kì í dárin. A ó gba ọ̀nà káńsù lọ báyìí. Ẹni tí ọwọ́ wa bá tẹ̀ nínú wọn, àwa náà ó fi ọ̀nà ọ̀run hàn án ṣùgbọ́n ká tó lọ, ẹ jẹ́ ká tọ́jú òkú arákùnrin yìí (Ọlátẹ́jú 2009:53).

Nígbà tí ìjà gbóná dé ojú rẹ, Anísẹ́ẹ̀rẹ́ tó saájú ogun Ẹgbẹ́ Bínúkonú tí agbègbè Ọ̀bọdà sọ̀rọ̀ si ọ̀gá Ọlọ́pàá:

***Anísẹ́ẹ̀rẹ́:*** Pa ẹnu ẹ mọ, Mọ́bà. O ò mọ̀ mí ni? Ẹ̀fún ni àbí èèdì, wọ́n ń dì ọ ni, àbí ìwọ lo ń di ara rẹ? Wèrè kọlù ọ ni àbí ìwọ lo kọlu wèrè? Kín lo gbójú lé? (Ọlátẹ́jú 2009:79).

Ìgbà tí àwọn Ẹgbẹ́ Bínúkonú da Màpó rú tán, wọ́n ya wọ ọgbà Agodi láti tú àwọn ènìyàn wọn tó wà ni àhámọ́ sílẹ̀.

***Aámúsà***: Ọgbà ẹ̀wọ̀n kò pé méjì ní ìbàdàn
Àgodi yìí kan náà ni.
***Aníṣẹ́ẹ̀rẹ́:*** Ọ̀gá Ọlọ́pàá, yàgò lọ́nà ká tóó sọ ara wa lóògùn. (Ọlátẹ́jú 2009:77).

Nínú àwọn àyọlò òkè yìí, ó hàn kedere pé ìfẹ̀tọ́dunni kan máa n fa èkejì lẹ́sẹ̀ ni, ní pàtàkì bí wọn bá tẹ ẹ̀tọ́ ọ̀pọ̀ ènìyàn lójú mọ́lẹ̀. Ikú tó pa Làmídì nínú *Iná Ràn* ló fà á ti àwọn Ẹgbẹ́ Bínúkonú agbègbè Ọ̀bọdà ṣe fárígá, tí wọn da ibùjókòó ìjọba ìbílẹ̀ tó wà ní Màpó ru, wọ́n bá akọ́dà àti ọlọ́pàá jà ti wọn sí lọ si ọgbà ẹ̀wọ̀n Agodi láti dá àwọn ọmọ ẹgbẹ́ wọn tí wọn ti mú saájú sílẹ̀ pẹ̀lú tìpátìkúùkù.

Ẹ̀tọ́ sí àìpọ́nilójú àti àìfiyàjẹni-lọ́nà-àìtọ́ tún jẹ́ títẹ̀ lójú nínú àwọn eré onítàn Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ nínú *Ìgbà Ló De*, àwọn òṣìṣẹ́ olówó orí àti Woléwolé tó lọ sí ìlú Ògbojò fiyà jẹ àwọn ará ìlú láìtọ́. Ajẹ́lẹ̀ kò faramọ́ èyí, ó bá àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba wí fún títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú.

Síwájú sii, nínú *Ìgbà Ló De* ìfẹ̀tọ́ ìwàláàyè dunni jẹ́ ohun tí Ládélé mú ni ọ̀kúnkúndùn. Èyí jẹ jáde nígbà tí àwọn ara ìlú Ògbojò pa àwọn olówó orí, Woléwolé àti Ológbojò láti fi ẹ̀hónú wọn hàn sí bí wọn ṣe n fiyà jẹ ará ìlú àti ìhà tí Ológbojò gan-an gẹ́gẹ́ bí ọba kọ si ìrẹjẹ yìí. Jagun tó jẹ́ asíwájú 'Ẹgbẹ́ Ayé' tó kọ ìyà àti ẹ̀gbin tí àwọn olówó orí àti woléwolé fi lọ̀ wọ́n ni:

***Jagun:*** Mànà. Nígbà tí àwọn ìjòyè kọ̀ láti ṣe ti àwọn ọmọ ìlú, tí èmi kìí si ṣe aṣiwèrè tí wọn ń fọwọ́ òsì tọ́ka sí ìlú rẹ̀ ni mo bá já àwọn ìjòyè ìyókù sílẹ̀ ní tèmi ni mo ń ṣe ti Ayé. Àbí? (Ládélé 1971:91).

Nígbà tí Ajẹ́lẹ̀ n ka ìdájọ́ rẹ̀ látẹnu Ògbufọ̀ ó ní:

***Ògbufọ̀***: Mo ti wádìí lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn márùn-un yìí, mo sì ti rí i pé àwọn ló gbó àwọn ènìyàn lọ́kàn láti ta ẹ̀jẹ̀ àwọn aláìṣẹ̀ sílẹ̀…. Nítorí náà, a ó yẹgi fún àwọn máràárún yìí lónìí ní ẹ̀gbẹ́ ilé Ológbojò níbẹ̀un (Ládélé 1971:99)

Ohun tí a rí fàyọ nínú àyọlo àti àlàyé òkè wọ̀nyí ni pé ìrẹjẹ ló ń bí ìfẹ̀tọ̀ ìwàláàyè dunni. Ìrẹ́jẹ̀ yìí sì tún pín sí mẹ́rin, olówó ń rẹ́ mẹ̀kún-nù jẹ, mẹ̀kún-nù ń rẹ́ ara wọn jẹ àwọn ọlọ́lá a máa tẹ ẹ̀tọ́ ọlọ́lá ẹgbẹ́ wọn mọ́lẹ̀, bákan náà àwọn mẹ̀kúnnù máa ń tẹ ẹ̀tọ́ àwọn ọlọ́lá mọ́lẹ̀ nípasẹ̀ dídá rògbòdìyàn sílẹ̀ nínú

èyí tí ẹ̀mí àwọn ọlọ́lá le bọ, èyí tó fi hàn pé bí ewùrẹ mẹ̀kúnnù ba bojú wẹ̀yìn, wọn yóò fi èpè félépè.

## Ẹ̀tọ́ Ọmọdé

Ẹ̀tọ́ ọmọdé lábẹ́ òfin jẹ èyí ti Àjọ Àgbáyé (UNO) fọwọ́ si ni ọdún 2000. Ní ọdún 2003 ni ìjọba Nàìjíríà fọwọ́ sí i tí o dì òfin. Ohun tí òfin ẹ̀tọ́ ọmọdé yìí túmọ̀ sí gẹ́gẹ́ bí àlàyé Àyàntáyọ̀ (2011:15) ni pé gbogbo ọmọdé lẹ́tọ̀ọ́ sí ìwàláàyè, wọ́n le ṣe ìkórajọ yòówù tó wù wọn. Wọ́n ní oore-ọ̀fẹ́ láti sọ èrò ọkàn wọn láì sí ìdíwọ́, bákan náà wọ́n lẹ́tọ̀ọ́ sí ààbò àti láti má ṣe jẹ́ kí wọn ní ìpín nínú ìninilára, ìfipábánilòpọ̀, ìfọmọsòwòẹrú àti ìlòkulò oògùn. Ẹ̀tọ́ ọmọdé ni láti ni ẹ̀kọ́ to yè kooro àti ìlera pípé. Ìyanisọ́tọ̀ látàrí ìbí, ẹ̀yà, ẹ̀sìn, èdè, ìsèlú, ìgbàgbọ́ àti àbùkù ara kò sì gbọdọ̀ jẹ́ ìpín wọn.

Àìgbọdọ̀ tẹ ẹ̀tọ́ ọmọde lójú mọlẹ̀ jẹ́ ara ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé kò dára láti máa fi ipò àgbà rẹ́ ọmọdé jẹ nítorí pé ẹyin ló ń di àkùkọ, ọmọdé òní ló ń bọ̀ wá di àgbà lọ́la. Gbogbo ẹbi lápapọ̀ ló lẹ́tọ̀ọ́ láti fi ìwá ọmọlúàbí kọ́ ọmọ agbó ilé wọn kí ó baà le di àgbà tí yóò wúlò. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé wọn a máa fi ẹgba bá ọmọdé wí bí ó bá ṣẹ̀, ìbáwí yìí kì í ṣe láti bà á láyé jẹ́ bí kò ṣe láti tọ́ ọ sọ́nà rere nítorí wọn gbà pé ọmọ tí a kò ba kọ́ ni yóò gbé ilé tí a kọ́ tà. Ìran Yorùbá korò ojú sí ìfiyà jẹ ọmọdé lọ́nà àìtọ́. Nínú *Wọ́n rò pé wèrè ni* Ládépò tí a tún mọ̀ sí Bàbá Rámá àti ìyàwó rẹ̀ Àwáwù gbìmọ̀ pọ̀ láti fi Àyọ̀ká (bí ọmọ ọdún méjìlá) tíí ṣe ọmọ ọ̀rẹ́ wọn ṣètùtù ọlà. Wọn tàn-an lọ sí ibi tí àwọn gbọ́mọgbọ́mọ ti gbé e lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn Irúnmọlẹ̀ tí yóò lò ó gẹ́gẹ́ bí ohun ètùtù ọlà fún Ládépò, ṣùgbọ́n orí kó o yọ. Àyọ̀ká ròyìn ohun tí ojú rẹ̀ rí ó ní:

***Àyọ̀ká:***
N ò lè jáde, n ò sì jẹun
Ìhòòhò ni mo ń rìn nínú ọgbà
Wọ́n ti gbaṣọ mi…
Wọ́n ní kí ẹnìkan pọn ọ̀bẹ tí wọn o fi dúńbú mi
Bí mo ti ń rìn kiri nínú òtútù
Mo debí kan àṣé ọgba ti ya
Mo sare jáde ní ìhòòhò
Nínú òkùnkùn láì mọ ibi tí mò ń lọ
Mo sáà ń sá lọ ni (Fálétí 1980:70).

Nígbà tí ọwọ́ pálábá wọn ségi, ìdájọ́ ikú àti ẹ̀wọ̀n ọlọ́jọ́ gbọọrọ ni Adájọ́ fún wọn nítorí ìfiyàjẹ ọmọdé ni ìwà yìí, ó sì jẹ títẹ ẹ̀tọ́ ọmọdé lójú mọ́lẹ̀.

Síwájú síi, Làbákẹ́ nínú *Àárò Wọ̀rọ̀kọ̀* tẹ ẹ̀tọ́ àwọn ọmọdé lójú mọ́lẹ̀. Ó kó àwọn ọ̀sọ́ọ̀rọ́ ọmọdébìnrin kan jọ sínú ilé kan, ó gbà àwọn ìgìrìpá ọkùnrin láti máa bá wọn lò pọ̀ títí oyún á fi dé. Bí wọn ba bímọ, a fun àwọn ọmọbìnrin wọ̀nyí ni *"owo oyún tí wọn bá a rù"*- ₦70, 000 fún èyí tó bá bí obìnrin,

₦80,000 fún èyí tó bá bí ọkùnrin. Yóó gba ọmọ tí wọn bá bí, yóò sì tà á fún àwọn tó fẹ́ gbà wọn tọ́, tàbí àwọn tí wọn fẹ́ fi wọ́n jóògùn.

Ní àsìkò tí Làbákẹ́ ń jíròrò pẹ̀lú Mosún ọ̀rẹ́ rẹ̀, ó ní:

***Làbákẹ́:*** Mo fẹ́ kí ó yé ẹ pé o kù nìbọn ń ró. Bí o bá ti ń rí irú àwọn ọmọbìnrin bẹ́ẹ̀ ni kí o máa fi wọ́n sọwọ́ sọ́dọ̀ mi. ìbáà ṣe èyí tó ti lóyún tàbí tí ó tí ì ni. Ṣé mo sọ fún ẹ pé mo ti ní àwọn ọmọkùnrin bíi mélòó kan lọ́dọ̀? (Àyándìran, 2016:27).

Nígbà tí Làbákẹ́ ń sọ̀rọ̀ láàrín àwọn ọ̀bàyéjẹ́ bíi tirẹ̀ ó ní:

***Làbákẹ́:*** Ẹ ṣeun alàgbà, ṣé ẹ mọ̀ pé iṣẹ́ tèmi yàtọ̀ sí tiyín díẹ̀? Àwọn ọmọbìnrin ni mo ń tọ́jú. Mo sì fẹ́ fi dá yín lójú pé ó lé ní àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin mẹ́ẹ̀ẹ́dógún tó wà lágbàlá mi. nígbà tí a bá fi máa rí oṣù kan síi, méjọ nínú wọn á ti bímọ. Kò sì le tó oṣù kejì tí àwọn tó kù yóò fi já ẹrù sílẹ̀. N ò ṣẹ̀ṣẹ̀ tún ní láti máa sọ fún yín ohun tí a n fi àwọn ọmọ tí wọn bá bí ṣe, èyí tí a ń tà, èyí ti a fi ń jóògùn (Àyándìran 2016:49).

Lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn ọwọ́ pálábá Làbákẹ́ àti àwọn akẹgbẹ́ rẹ̀ ṣégi. Ìdájọ́ ẹ̀wọ̀n gbére ni adájọ́ dá fún Làbákẹ́ àti àwọn alábàásiṣẹ́pọ̀ ibi tí wọn kò jẹ́ kí ìlú Ayépéjú o rójú nipa ìwà jàgídíjàgan àti ìdàlúrú tí wọn hù nínú ìwé *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀.* Gẹ́gẹ́ bí tíọ̀rì ìbágbépọ̀ ẹ̀dá ti fi yé ni, a ó ri i pé òǹkọ̀wé lo àwọn akópa inú eré onítàn yìí láti tú àṣírí àwọn ìwà ibi tó ń ṣẹlẹ̀ ni àwùjọ ni, àwọn ìwà bíi ìfènìyàn ṣètùtù ọlà, ìfẹ̀tọ́ ọmọdé dùn-ún, àwọn tó ń sin àwọn olóyún bi ẹni sin ewúrẹ́, kí wọn baà le ta ọmọ tí wọn bá bí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí òpin yóò bá dé bá ìṣòro àwùjọ yìí, àwùjọ gbọ́dọ̀ fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró bí ó ṣe sẹlẹ̀ nínú àwọn ìwé tí a yẹ̀wò. Láti yóò sì dẹ́kun àwọn ìwà ìbàjẹ́ tí ó ń mú ìfàsẹ́yìn bá àwùjọ wa.

## Okùnfà Títẹ Ẹ̀tọ́ Ẹni Lójú Mọ́lẹ̀

Ohun tó lè ṣokùnfà títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú pọ̀. Àrífàyọ tí a ṣe nínú eré onítàn fihàn pé ìwà ìjẹgaba lórí ẹni tó ti di bárakú fún ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ ilé ọlá a máa mú wọn rẹ́ àwọn mẹ̀kúnnù jẹ, èyí á sì bí ìtẹtọ́-ẹni-lójú-mọ́lẹ̀. Púpọ̀ nínú àwọn ọmọ ọba, ìjòyè tàbí olórúkọ láàrin ìlú máa ń jẹ ayé fa-mi-létè-n-tutọ́, èyí tó jẹ́ ìwà títẹ ẹ̀tọ́ ẹlòmíràn lójú mọ́lẹ̀ tí àwùjọ korò ojú si. Àpẹẹrẹ ni bí Ọláyìíòtán ṣe ta ọfà lu ọkùnrin tó ń sinmi nínú oko rẹ̀ (66), tí Òbe sì fi idá bẹ aláààrù lórí nínú Baṣọ̀run Gáà (72). Yàtọ̀ sí èyí, àwọn méjèèjì tún gún Akínkúnmi àti onírárà bí ẹṣin (90). Irú ìwà yìí kan náà ni àwọn ẹrú Ẹfúnṣétan hù si Ògúnjìnmí akọ̀pẹ tí wọn fi ẹsun olè jíjà kàn, ti wọ́n sì lù ú dé ojú ikú nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* (17).

Nígbà mìíràn a ṣàkíyèsí ìhònú ẹlẹ́wù ẹtù gẹ́gẹ́ bí Ìṣẹ̀lá (1991) ṣe fìdí rẹ̀ múlẹ̀, a tún máa fa ìtẹ̀tọ́-ọmọnìyàn-lójú-mọ́lẹ̀. Bí àpẹẹrẹ Baṣọ̀run Gáà mọ̀-ọ́n-mọ hu ìwà kò-sí-ohun-tí-ẹ-ó-fi-mí-ṣe láti fi ẹ̀hónú hàn sí ètó ìṣèjọba Ọba Abíọ́dún ni. Òun tí ó pe àwọn ẹrú àti mọ̀lẹ́bí rẹ̀ ni ìbẹ̀rẹ̀ ìṣèjọba Abíọ́dún pé kí wọn jáwọ́ nínú ìwà ti ó lè da omi àlàáfíà ìlú rú (52) náà ni kò rí ohun tó burú mọ́ nínú bí Òbe ṣe bẹ aláàárù lórí, tí òun fúnraarẹ̀ sì fi ọmọ Ọba ṣètùtù ọlà. Yàtọ̀ sí èyí Gáà ń dọ́gbọ́n fi hàn pé inú òun kò dùn sí ìṣèjọba tí kò fún òun bí àgbà ìjòyè láǹfààní láti dé ipò ọba. Ó ní kí wọ́n yéé pe òun ní kábíyèsí (5-6). Àsìlò agbára a tún máa fa ìtẹ̀tọ́-ọmọnìyàn lójú. Nínú àṣà ilẹ̀ Yorùbá, igbákejì òrìṣà ni wọn ka ipò ọba sí, ìdí nìyí tí wọn fi máa ń pè wọ́n ní kábíyèsí (kí-á-bi-ọ́-kò-sí), èyí tí ó túmọ̀ sí pé kò si ẹ̀dá kan tí ó le yẹ ọba lọ́wọ́ wò lórí ohun yòówù tí ó bá ṣe. Ipò agbára tí àṣà gbé wọ̀ wọ́n yìí máa ń pa òmíràn nínú wọn bí ọtí, tí wọn á sì si agbára náà lò láti tẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú. Àpẹẹrẹ ni bí ọba Májẹ̀ẹ́ógbé ṣe pàṣẹ kí wọ́n lọ gbé orí Ìlọ̀rí tíí ṣe bàbá ọ̀kan nínú àwọn ayaba wá nítorí pé ìyẹn báa sẹ̀fẹ̀ pe kò sán-angun tó bàbá òun. Ọba ṣe èyí láti jẹ́ kí ayaba mọ̀ pé kìí ṣe ìrísí ni a fi ń ṣèlú bí kò ṣe agbára òṣèlú, àti pé agbára ju agbára lọ. Gáà ṣàlàyé ìṣẹlẹ̀ yìí:

***Gáà:***

Májẹ̀ẹ́ógbé ló dolóyè ló gbàgbé
Pe ènìyàn táa bá fẹ́mọ lọ́wọ́ ẹ
Eléyíinì òun làna ẹni
Májẹ̀ẹ́ógbé ló pa Ìlọ̀rí oníbàtá
Nílé onílù ni Jàbàtá
Nibi tọ́mọ wọn gbé ń tarú tata
Kó tó wá dayaba
Ọmọ Ìlọ̀rí ló ń bọ́ba sẹ̀fẹ̀
Ó ń fàwàdà bọ́ba lòfẹ̀
Ó ní ọkọ òun kò sán-angun tó bàbá òun
Ọba ni kí wọn ó lọ gbórí Ìlọ̀rí wá
Òkìkì kàn
Kọ́mọ rẹ̀ ó lè mọ̀ pé
Ẹja tí ń dàámú ibú kò to nǹkan (Fálétí 1972:4).

A tún ṣàkíyèsí pé ìgbìyànjú láti kó ọrọ̀ jọ tún jẹ́ ọ̀kan lára okùnfà ìtẹ̀tọ́-ọmọnìyàn lójú nínú àwọn eré onítàn tí a yẹ̀wò. Ìfẹ́ owó ló mú kí Làbákẹ́ nínú *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀* máa sin àwọn ọmọge bí àwọ́nsìn ewúrẹ́, tí ó sì ń kó ọmọ wọn tà fún àwọn tí wọn yóò fi wọn ṣètùtù ọlà ní kété tí wọn bá ti bímọ (49). Síwájú síi, ìfẹ́ owó kan náà ni ó mú kí Ọlátúnjí àti Ògúnrìndé ó ṣètò bí wọn ṣe jí Ọ̀gbẹ́ni Àpáta gbe, tí wọ́n sì gba mílíọ̀nù márùn-ún náírà kí wọ́n tó tú Àpáta sílẹ̀ nínú *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀*. (69)

Yàtọ̀ sí ti ẹ̀hónú tí Gáà ń fi hàn nípa ìwà mo-ga-jòfin-lọ tí òun, ẹrú àti mọ̀lẹ́bí rẹ̀ ń hù, ó fi ẹnu ara rẹ̀ sọ pé owó ṣe kókó nínú ètò ìṣèjọba àti pé òun fẹ́ dọlọ́rọ̀, ó sì fi ọmọ ọba ṣètùtù ọla.

***Gáà:*** Hun-un….
Àwọn ẹni tí ò gbọ́n ẹni tí kò mọ̀ràn
Nwọn a ní nígbàtáwọn fi ọ́ jọba
Kí lo tún wá débi ọsẹ àwúre?
Wọn ò mọ̀ pé
Kò sohun tẹnikan kìí dọ́gbọ́n sí
Bénìà bá jọba bí a ṣegbòogi
Bó pẹ́ títí nwọn a máa yọ ni lọba (Fálétí 1972:95).

Síwájú síi, ìgbìyànjú àtilówó ti Ládépò-Baba Rama láti lè máa fi ṣe fújà ní àwùjọ ló mú kí ó pinnu láti tan Àyọ̀ká ọmọ ọ̀rẹ́ rẹ̀ lọ sí ibi tí wọn yóò ti báa fi ṣètùtù ọlà nínú *Wọ́n Rò Pé Wèrè Ni* (58).

Ohun mìíràn tí ó tún máa ń fa ìtẹ̀tọ́-ọmọnìyàn lóju bí ó ti farahàn nínú eré onítàn ni ìwà àìní sùúrù àti inúfùfù. Àwọn àléébù ìwà méjèèjì yìí máa ń ṣe atọ́nà fún títẹ ẹ̀tọ́ ẹlòmíràn lójú mọ́lẹ̀ nígbà tí wọ́n bá sún kàngiri. Nínú *Àarẹ-àgò Aríkúyẹrí,* Asiyanbí ìyáálé Ògúnrìndé Ajé fi ẹ̀sùn kan Fátọ́lá ti wọn jọ jẹ́ ìyàwó ọkọ kan náà pé òun ló fi májèlé pa àwọn ọmọ Adépèlé mẹ́ta ti wọn kú lọ́jọ́ kan náà ni tẹ̀lé-n-tẹ̀lé. Asiyanbí sọ fún ọkọ wọn pé òun lọ sí ilé Babaláwo láti wádìí ikú àwọ́kú nínú ìdílé wọn. Dípò tí ọkọ wọn kì bá fi mú sùúrù, kí ó fi pẹ̀lẹ́kùtù wádìí ìsẹ̀lẹ̀, ó gbà pé òtítọ́ ni Aṣiyanbí sọ, ó sì fi ìbínú ta Fátọ́lá lọ́fà ti ìyẹn sì gbabẹ̀ kú (29). Lẹ́yìn-ò-rẹyìn ni àsírí tóó tú pé Aṣiyanbi gan-an ló wà nídìí ọ̀rọ̀ nítorí pé ó ń jowú Fátọ́lá tó gbayì tó gbẹ̀yẹ nínú rárà sísun lọ́jọ́ tí ọkọ wọn ń bọrí ni. Àìfarabalẹ̀ wádìí okùnfà ikú àwọn ọmọ rẹ̀ ló mú kí Àarẹ-àgò Ògúnrìndé Ajé tẹ ẹ̀tọ́ ìwàláàyè ìyàwó rẹ̀ Fátọ́lá mọ́lẹ̀, tí ó sì fi ikú gbíg-bóná pa á (29).

## Ìbáṣepọ Láàrín Àwọn Atẹ̀tọ́-ẹní-lójú-mọ́lẹ̀ àti Ẹlẹ́tọ̀ọ́

Àkíyèsí láti inú àwọn eré-onítàn tí a gbe yẹ̀wò ni pe àwọn ajẹgaba wọ̀nyí kìí sáábà tẹ ẹ̀tọ́ mọ̀lẹ́bí wọn lójú mọ́lẹ̀. Ẹni tí kò bá wọn tan ni wọn sáábà máa n rẹ́jẹ tàbí fi ẹ̀tọ́ wọn dùn wọ́n àyàfi èèsì lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan bíi irú ti Ògúnrìndé Ajé tó fibínú pa ìyàwó rẹ̀. Ọmọ ọlọ́mọ ni Ládépò fẹ fi ṣètùtù ọlà, àwọn tí Òbe àti Láyìíòtán gùn lẹ́ṣin tàbí dáná sun ilé wọn kì í ṣe mọ̀lẹ́bí wọn.

Ohun mìíràn tí a tún kíyèsí ni pé tọkùnrin tobìnrin ló ń hùwà ìfẹ̀tọ́dunni, tọkùnrin tobìnrin sì ni wọn n fi ẹ̀tọ́ dùn. Yàtọ̀ sí èyí, àgbà tí ó ti tójúú bọ ni àwọn afẹ̀tọ́dunni wọ̀nyí, kò sí ọmọdé nínú wọn. Bí wọn ṣe ń fi ẹ̀tọ́ dún ọmọdé, ni wọn fi n dun àgbà láì fi ti ìlànà ìsẹ̀dánìyàn àti ẹ̀sìn ṣe. Lára àwọn ọkùnrin

tó hùwà ìfẹ̀tọ́dunni ni Baṣọ̀run Gáà, Òbe àti Ọláyìíòtán nínú *Baṣọ̀run Gáà*. Àdìsá, Ògúnrìndé àti Ọlátúnjí nínú *Àárò Wọ̀rọ̀kọ̀,* Ààrẹ-Àgò Ògúnrìndé Ajé nínú *Ààrẹ-Àgò Aríkúyẹrí,* Aníṣẹ́ẹ̀rẹ́, Àmùdá àti Yésúfù nínú *Iná Ràn*. Bẹ́ẹ̀ ni a rí Jagun, Júawo àti Adégún nínú *Ìgbà Ló De* àti Ládépò (Baba Rámá) nínú *Wọ́n Rò Pé Wèrè Ni*. Àpẹẹrẹ àwọn obìnrin tó fi ẹ̀tọ́ dùnnìyàn ni Làbákẹ́ nínú *Àárò Wọ̀rọ̀kọ̀,* Ìyálóde Ẹfúnṣetan nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* àti Ìyá Ilé orí nínú *Baṣọ̀run Gáà*. Àkíyèsí wa ni pé àgbà tó tó ojúúbọ̀ ni àwọn afẹ̀tọ́dunni lọ́kùnrin àti lóbìnrin wọ̀nyí. Ní ti àwọn ọkùnrin tí a fi ẹ̀tọ́ dun, a rí àpẹẹrẹ Ìtáwuyì nínú *Ẹfúnṣetan Aníwúrà,* Akínkúnmi àti Olúbùṣe nínú *Baṣọ̀run Gáà*, àti Làsísì nínú *Iná Ràn*. Ní ti àwọn obìnrin, a rí àpẹẹrẹ Adétutù àti Àwẹ̀ró nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà,* àti Ìyá gbogbo nínú *Ìgbà Ló De*. A kò sài rí àwọn ọmọdé tí a fi ẹ̀tọ́ dùn bíi Àyọ̀ká nínú *Wọ́n rò pé wèrè ni*, bákan náà ni a rí Ṣadé, Tutù, Bímbọ́ àti Múbọ̀ nínú *Aàrò Wọ̀rọ̀kọ̀*.

Àkíyèsí mìíràn ni pé bí àwọn Ọlọ́lá ṣe ń tẹ ẹ̀tọ́ mẹ̀kúnnù lójú mọ́lẹ̀, ni wọn ń tẹ ti ọlọ́lá ẹgbẹ́ wọn lójú pẹ̀lú. Àwọn mẹ̀kúnnù náà máa ń tẹ́ ẹ̀tọ́ àwọn ọlọ́lá mọ́lẹ̀ lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan, àwọn náà pẹ̀lú a sì máa tẹ ẹ̀tọ́ mẹ́kúnnù ẹgbẹ́ wọn mọ́lẹ̀ pẹ̀lú. Àpẹẹrẹ àwọn Ọlọ́lá tó ń tẹ ẹ̀tọ́ mẹ̀kúnnù lójú ni bí Òbe àti Ọláyìíòtán ṣe gun onírárá àti Akínkúnmi bí ẹ̀sín, tí Baṣọ̀run Gáà sì ṣekú pa Akínkúnmi nínú *Baṣọ́run Gáà*. Òmíràn ni bí Ògúnrìndé Ajé ṣe pa Fátọ̀lá, tí Làbákẹ́ sì ń kó ọmọ ti àwọn ọmọbìnrin to ń bọ́ tà fún àwọn alágbára tó nílò wọn nínú *Àárò Wọ̀rọ̀kọ̀*. Àpẹẹrẹ ẹ̀hónú mẹ̀kúnnù si àwọn ọlọ́lá èyí tó sáábà máa ń mú awuyewuye dání ni níbi ti wọn ti tẹ ẹ̀tọ́ àwọn ọlọ́lá mọ́lẹ̀, èyí jẹyọ nígbà tí àwọn ọmọ Ẹgbẹ́ Ayé nínú *Ìgbà Ló De* dá rògbòdìyàn sílẹ̀ èyí tí ó mú ẹ̀mí Ológbojò, àwọn Woléwolé àti Olówó-orí lọ. Àpẹẹrẹ mìíràn wà nínú *Iná Ràn* níbi ti àwọn Ẹgbẹ́ Bínúkonú bá àwọn olówó orí wọ̀yá ìjà, tí wọn kọlu Akọ́dà àti Ọlọ́pàá, tí wọn sì dá àwọn ẹlẹ́wọ̀n tó wà lọ́gbà Agodi sílẹ̀. Bí a ti ri àpẹẹrẹ mẹ̀kúnnù ti o ń tẹ ẹ̀tọ́ ẹgbẹ́ rẹ mọ́lẹ̀ náà ni a rí àwọn ọlọ́lá tí wọn ń kọjú ìjà sí ara wọn. Àpẹẹrẹ tí mẹ̀kúnnú ni bí Bàbá Rama ṣe tẹ ẹ̀tọ́ Àrẹ̀mú lójú nípa gbígbé ọmọ rẹ̀ láti fi ṣe òògùn owó. Síwájú síi a ri àwọn ti a le pe ni ọlọ́lá tí wọn ń tẹ ẹ̀tọ́ ara wọn lójú nípa gbígbógun ti ara wọn. Ìṣọ̀lá (1991:36) pe irú ìṣẹ̀lẹ̀ báyìí ni "Èhónú Ẹlẹ́wù Ẹtù". Ó ṣàlàyé pé ọ̀rọ̀ òṣèlú ló sáábà máa ń ṣe okùnfà irú wàhálà bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni bí Látòósa ṣe saájú àwọn tó lọ jẹ ilé Ẹfúnṣetán run nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, tí Ààrẹ-Ọ̀nà Kakanfo Ọyalabí sì darí àwọn tó lọ gbogun ti Gáà Ọṣọ̀run nínú *Baṣọ́run Gáà*. Èyí n wáyé bẹ́ẹ̀ nígbà ti ọlọ́lá kan bá sì agbára lò tí àpapọ̀ ìlú sì bínú síi láti fi àbùkù kàn-án. Ohun ti a ri fàyọ láti inú àlàyé òkè yìí ni pé kò sí ìpín ti ìṣe kò sì, kò sí ẹni ti kì í tẹ ẹ̀tọ́ ara wọn lójú, káríayé aṣọ oníkọ̀kọ́rọ̀ ni.

## Ètó Ìdájọ́

Eré ipá kìí bi ọmọ rere, bí kò bí ìkúùkù, a bi ọgbẹ́ ńlá ni ọ̀rọ̀ ìfẹ̀tọ́dunni. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ìfẹ̀tọ́dunni máa ń já sí ikú, òfò ẹ̀mí, ìpalára tàbí ìkùnsínú. Ìfẹ̀tọ́dunni le yọrí sí ìfẹ̀hónúhàn ti yóò sì mú rògbòdìyàn dání. Nígbà tí Lágbájá bá fi ẹ̀tọ́ dun Tàmẹ̀dù, Tàmẹ̀dù lè fẹ́ gbẹ̀san, tí ẹ̀san rẹ̀ yóò wa burú ju ìwà tí Lágbájá hù lọ, tí wàhálà àti rògbòdìyàn sì le sẹlẹ̀, tí ó sì jẹ́ pé ìdájọ́ ni yóò tẹ̀lé e. Nígbà mìíràn rògbòdìyàn a maa di ìjà ìgboro èyí tí ó le fa ofo ẹ̀mí àti dúkìá.

Oríṣìí ètò ìdájọ́ mẹ́ta tó farahàn nínú àwọn eré onítàn tí a sàyẹ̀wò ni ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀, ìdájọ́ ni ìlànà òfin àti ìdájọ́ lọ́wọ́ ara ẹni. Ohun tí ìdájọ́ lọ́nà àṣà ìbílẹ̀ túmọ̀ sí ni pé kí ẹni tí wọn fi ẹ̀tọ́ dùn mú ẹjọ́ ẹni tí ó fi ẹ̀tọ́ dùn-ún lọ sọ́dọ̀ àwọn àgbà tí ó bá wà nítòsí. Irú àwọn àgbà báyìí máa ń sáábà jẹ́ Baálé, ó lè jẹ́ baálẹ̀ tàbí Ọba. Àwọn àgbà wọ̀nyí ti o máa ń sáábà jẹ́ tọkùnrin tobìnrin ilé yóò pe àwọn ti ọ̀rọ̀ kàn pẹ̀lú ẹlẹ́rìí láti fidí ẹ̀sùn múlẹ̀, wọn yóò sì sọ̀rọ̀ lórí ibi ti ẹnìkọ̀ọ̀kan ti jàre tàbí jẹ̀bi kí wọn tó gbé ìdájọ́ kalẹ̀. Bí ó bá jẹ ìlú ńlá ni ọba àti ìjòyè ni yóò jẹ́ ìgbìmọ̀ ìdájọ́, ọba ni yóò sì gbé ìdájọ́ kalẹ̀ lẹ́yìn ìjíròrò àwọn ọmọ ìgbìmọ̀. Nínú iṣẹ́ yìí a rí ibi tí àgbà ìjòyè-Ààrẹ-àgò Ògúnrìndé Ajé ti tẹ ẹ̀tọ́ ìwàláàyè ìyàwó rẹ̀ Fátọ̀lá lójú mọ́lẹ̀ nínú *Ààrẹ-àgò-Aríkúyẹrí* nípa pé ó pa á, ẹjọ́ rẹ̀ de ọ̀dọ̀ Baṣọ̀run Ògúnmọ̀lá, tíí ṣe alákòóso Ìbàdàn lásìkò náà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ògúnrìndé Ajé jà raburabu láti dojú ìdájọ́ delẹ̀ nípa gbígbé àbẹ̀tẹ́lẹ̀ ránsẹ́ sí àwọn ìjòyè, Ògúnmọ̀lá kò gbà, ó dájọ́ bí o ṣe yẹ lẹ́yìn ìwádìí nípa bí iṣu ṣe kú àti bí ọ̀bẹ ṣe bẹ́ ẹ́. Ó dájọ́ ikú fún Aṣiyanbí àti Ògúnrìndé Ajé, ó sì dá Adépèlé sílẹ̀.

Nínú ìpàdé ìgbìmọ̀ tó ń sàkóso ìlú Ìbàdàn lábẹ́ ìdarí Ààrẹ Látòósà ni wọ́n ti gbà pé kí wọn fi òpin sí ayé ìjẹkújẹ àti ìtẹ̀tọ́ọmọnìyàn lójú ìyálóde Ẹfúnṣetán Aníwúrà nínú *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*. Bákan náà ni a rí ibi tí Aláàfin Abíọ́dún ti paṣẹ̀ ìdájọ́ ikú oró fun Gáà nínú *Baṣọ̀run Gáà.*

Oríṣìí ìdájọ́ kejì ni èyí tó wáyé ni kóòtù. Ìdájọ́ kóòtù wáyé láti ẹnu àwọn adájọ́ tí ìjọba yàn. Adájọ́ ló dájọ́ ikú fún àwọn apaniṣètùtù ọlà àti ẹ̀wọ̀n ọlọ́jọ́ gbọọrọ fún Ládépò. Bákan náà Ajẹ́lẹ̀ ló dá ẹjọ́ ikú fún Júawo, Adégún àti àwọn ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ tí wọn pa Ológbojò àti olówó orí nínú ìwé *Ìgbà Ló De*.

**Ògbifọ̀:** Tí ẹnìkan tàbí àgbájọ àwọn èèyàn kan bá kó ara wọn jọ láti gbẹ̀san ìkùnsínú kan, tí wọn sì ti ipa bẹ́ẹ̀ pa èèyàn, irú àwọn èèyàn bẹ́ẹ̀ níláti kú gẹ́gẹ́ bí òfin. Nítorí náà, òní ni a ó yẹgi fún àwọn máràárún yìí lónìí ní ẹ̀gbẹ́ ilé Ológbojò níbẹ̀un (Ládélé 1971:99).

Adájọ́ kóòtù pẹ̀lú ló dájọ́ ẹ̀wọ̀n gbére fún Làbákẹ́, Bùkóyè àti àwọn adàlúrú yòókù ni ìlú Ayépéjú bí ó ṣe wà nínú *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀.*

Ìdájọ́ mìíràn tó farahàn nínú iṣẹ́ yìí ni èyí ti àwọn ará ìlú ṣe lọ́wọ́ ara wọn lái lo òfin ìjọba. Èyí sáábà máa ń wáyé bí ìjọba tàbí asojú ìjọba bá ń tẹ ẹ̀tọ́ àwọn ará ìlú lójú mọ́lẹ̀ fún ọjọ́ pípẹ́. Ìfẹ̀hónúhàn àti irú ìdájọ́ báyìí sáábà máa ń lọ ni sísẹ̀-n-tẹ̀lé. Àpẹẹrẹ irú ìdájọ yìí ni àwọn ará ìlú Ògbojò ṣe fún Ológbojò, olówó orí àti àwọn Woléwolé nínú ìwé *Ìgbà Ló De* níbi tí wọn ti bá ikú pàdé lásìkò ìfẹ̀hónúhàn. Irú ìdájọ́ bí èyí tún wáyé nínú *Iná Ràn* níbi tí àwọn ará ìlú Ọbọda àti agbègbè rẹ̀ ti kọjú ìjà sí àwọn olówó orí àti ọlọ́pàá nítorí bí wọn ṣe fi ìyà jẹ Làsísí ọ̀kan nínú wọn dé ojú ikú.

***Aníṣẹ́ẹ́rẹ́:*** Ó tó!
*(Ìlú àti orin dúró)*
Òkè Màpó la dé yìí. Ẹ múra gírí, àwọn ọlọ́pàá lè wà níbẹ̀. Ẹ má bẹ̀rù, ẹ má sojo. Ajá kìí jámọ lẹ́yìn ẹkùn. Èèwọ̀. Ó yá, ẹ nìsó. Àwọn Ọlọ́pàá nù-un. Ẹ fi obi yin ṣẹ́nu. Ẹ máa fi ẹsẹ̀ kan fò kálọ. Wọn kò le rí wa. Ẹ kálọ…. (Ọlátẹ́jú 2009:71).

A ṣàkíyèsí pé wàhálà to máa ń súyọ nípasẹ̀ síṣe ìdájọ lọ́wọ́ ara ẹni kìí ṣe kekere, lọ́pọ̀ ìgbà aláìsẹ̀ máa ń jìyà, ó sì máa n mú ìṣòfò ọ̀pọ̀ ẹ̀mí àti dúkìá lọ́wọ́, bí àwọn ti wọn tẹ ẹ̀tọ́ wọn mọ́lẹ̀ bá tún gbẹ̀san, ṣe ni ìjà yóò máa ran mọ̀ọ́n bí iná ìgbà ẹ̀ẹ̀rùn. Pípa ti àwọn Ẹgbẹ́ Ayé pa Ológbojò, woléwolé, olówó orí àti alága ẹgbẹ́ ọmọ ìbílẹ̀ ló ṣokùnfà bí Ajẹ́lẹ̀ ṣe dájọ́ ikú fún àwọn márùnún mìíràn ti wọ́n kópa nínú rògbòdìyàn náà nínú *Ìgbà Ló De.*

## Àgbálọgbábọ̀

Ó hàn gbangba nínú àpilẹ̀kọ yìí pé àwùjọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ẹ̀yà tó wà ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ti ní ìmọ̀ kíkún lórí ohun tí a ń pè ni ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn láti ìgbà ìwásẹ̀, inú àṣà wọn lo wà, wọn sì ni ìlànà ìdájọ́ to múnádókó láti fi fìyà jẹ afẹ̀tọ́dunni. Nígbà mìíràn àìtètè jẹ́ kí ìjọba mọ̀ nípa ìṣòro tó ń kọjú ará ìlú máa n sokùnfà síṣe ìdájọ́ lọ́wọ́ ara ẹni, bí ará ìlú kò bá sọ̀rọ̀ sókè, tí wọn ń fi ìṣòro wọn ṣe iṣó inú ẹ̀kú àrúnmọ́ra, bí ó bá dé àsìkò tí ó fẹ́ ga ju ẹ̀mí wọn lọ, wọn lè pinnu ṣíṣe ìdájọ́ lọ́wọ́ ara wọn.

Síwájú sìi, ó tún hàn nínú iṣẹ́ yìí pé ìjọba tí kò bá kọbi ara sí àròyé ara ìlú nípa àwọn ìyọnu kan tí wọn ń ní, tàbí ìṣòro tó ń kojú wọn le ṣe okùnfà ìwọ́dè, ìwọ́de le ṣe kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ di ìfẹ̀hónúhàn, tí ìfẹ̀hónúhàn yóò sì paradà di rògbòdìyan. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ tí ó jẹyọ nínú eré-onítàn tí a yẹ̀ wò ló fi ara pẹ́ bí ìjọba ko ṣe kọbiara sí ìnira tí ẹ̀ka Ọlọ́pàá tó ń gbógun ti ìdigunjalè (SARS) ń mú bá ará ìlúní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà èyí tó ṣe òkùnfà ìwọ́de "Ṣọ̀rọ̀ Sókè" (END SARS) tó wáyé ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní oṣù kẹwàá ọdún 2020 nínú èyí tí ọ̀pọ̀ ẹ̀mí ara ìlú, agbófinro àti dúkìá ti sòfò.

Iṣẹ́ yìí tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, ìwà ìkórá-ẹni-ní-ìjánu ṣe pàtàkì nínú ìgbé ayé ẹ̀dá, kí gbogbo ọmọ orílẹ̀ èdè ṣetán láti pa òfin mọ, kí wọn sì sọ́ra fún ìjẹgaba lórí ẹnìkejì wọn nítorí ìgbìyànjú àti jẹgàba àti kọ̀wọ̀sí ni okùnfà rúkèrúdò ní àwùjọ.

Bákan náà, iṣẹ́ yìí tún mẹ́nuba àwọn okùnfà ìfẹ̀tọ́-ẹni-duni. Ó hàn gbangba pé àṣìlò ipò, ìjẹgàba lórí ọmọlakẹjì, ìfọwọ́-ọlá-gbáni-lójú, ìgbìyànjú àti kó ọ̀rọ̀ jọ, àti ìkọlùra ojú-àmúwáyé òun ìfẹ̀hónú hàn a máa bí ìtẹ̀tọ́-ọmọnìkejì lójú. Bákan náà, ni iṣẹ́ yìí tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìpín ipò kò ní i ṣe pẹ̀lú ìrẹ́jẹ àti títẹ-ẹ̀tọ́-ẹni-lójú. Bí olówó ṣe ń rẹ́ mẹ̀kúnnù jẹ náà ni mẹ̀kúnnù ṣe lè tẹ ẹ̀tọ́ ọlọ́rọ̀ mọ́lẹ̀, pàápàá nígbà tí ọ̀rọ̀ bá ti dàbí  ti ewúrẹ́ tí a sún kan ògiri.

Ní ìkádìí, ó ṣe pàtàkì kí àwọn ọmọ ìlú kọ̀ọ̀kan ní òye nípa kí ni ojúṣe àti ẹ̀tọ́ rẹ̀ lábẹ́ òfin. Bí oníkálùkù bá mọ ẹ̀tọ́ rẹ̀, yóò le yàgò fún ṣíṣe ohun àìtọ́, yóò sì lè jà fún ẹ̀tọ́ rẹ lábẹ́ òfin, bí ẹnìkan bá sì fẹ́ fi ẹ̀tọ́ rẹ̀ dùn-ún tàbí fi ìyà jẹ ẹ́ láìnídìí yóò lè mọ ìgbésẹ̀ tó yẹ láti fi kọ ìyà náà. Kí ìjọba máa ṣe ìkéde àti ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lóòrèkóòrè lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lábẹ́ òfin. A gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ará ìlú mọ ibi tí wọn ti lè lọ fi ẹjọ́ sùn bí ẹnìkan bá ń tẹ ẹ̀tọ́ wọn lójú mọ́lẹ̀.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Adégbìtẹ́, K. 2014. 'Fundamental Human Rights' A paper presented at the NYSC 2014 Batch C Orientation Course at Permanent Orientation Camp, Ìṣẹ́yìn.

Adéjùmọ̀, A. 2018. "Thematization and Perspectivisation of Human Rights and Development in Yorùbá Poetry". An Article in *Àkùngbá Journal of Linguistics and Literatures.* No 9, Special Edition, Pp. 15-25.

____________ 2019. Articulations of Human Rights Ideas in Contemporary Yorùbá Poetry. A chapter contribution in *Creative incursions cultural representations of Human Rights in Africa and the Black Diaspora.* Durham. Carolina Academic Press. Borah A, Falola B, Falola Toyin (Eds) pp 117-134.

Adéyẹmí, G. 2019. 'Limitation to Human Rights'. An Article in ***Ọkàn-Heart***. The 8th Edition of annual publication of Ògbómọ̀ṣọ́ Baptist High School, Ògbọ́mọ̀ṣọ́. Pg.15.

Akíntọ́lá, A. 1999. *Yorùbá Ethics and Metaphysics.* Ògbómọ̀ṣọ́ Valour Publihing Ventures.

Akínyẹmí, B. 2000. "Your rights, my rights, Human rights". A lecture delivered at 2nd Lam Adesina Lecture for Peace and Good Governance, Ìbàdàn on 23/11/2000.

Anyaegbunam, E. 2014. E*ssentials of the Nigerias 1999 Constitution as amended.* Ìbàdàn African Centre for Parliamentary and Constitutional Studies.

Àyándìràn, A. 2016. *Ààrò Wọ̀rọ̀kọ̀*. Ìbàdàn: Extension Publications Limited.
Àyántáyọ̀, J. 2011. *Child Rights in Literary Genres and Religious Scriptures.* Ibadan: African Publishing Company.
Bible Society of Nigeria 2000 *Bíbélì Mímọ́* Lagos: Bible Society of Nigeria.
Chiroma, M. 2010. *Challenges of Enforecement of Fundamental Human Rights under the Constitution of the Federal Republic of Nigeria",* PGDLD Project, Nigeria Institute of Advance Legal Studies, University of Lagos Campus.
Fálétí, A. 1972. *Baṣọ̀run Gáà.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Books and Publication Company Nigeria Limited.
Fálétí, A. 1980. *Wọ́n rò pé wèrè ni*. Ìbàdàn University Press Ltd.
Federal Republic of Nigeria 2011. *1999 Constitution with Amendment 2011.*
Hornby, A. 2004. *Oxford Advanced Learners Dictionary of Current English.* Oxford: Oxford University Press.
Ìsọ̀lá, A. 1970. *Ẹfúnṣetán Aníwúrà.* Ìbàdàn: University Press Plc.
__________ 1991. "Indigo's Revolt", An Article in Research in Yorùbá language and Literature No 1 Pp. 29-37.
Ládélé, T. 1971. *Ìgbà Ló De.* Ìbàdàn: Oníbonòjẹ́ Books and Publication Company Nigeria Ltd.
Ògúnníran, L. 1977. *Ààrẹ̀-Àgò Aríkúyẹrí.* Lagos: Macmillan.
Ògúnṣínà, B. 2006. *Sociology of the Yorùbá Novel. An Introduction.* Ìlọrin: Integrity Publication.
Ọlátẹ́jú, A. 2009. *Iná Ràn*. Ìbàdàn: DB Martoy Books.
Ọnadẹ́kọ̀, T. 2008. 'Yorùbá Traditional Adjudicatory System' A chapter Contribution in *African Study Monographs* 2008. Pp. 28-36.
Ràímì, B. 1990. Yorùbá System of Adjudication in Contemporary Society. *Só Dáa Bẹ́ẹ̀*? (A BCOS Weekly Programme) as a case study. M.A. Project: Depatment of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.
Tàbí-Àgòrò, A. 2008. Traditional System of Adjudication as reflected in Yorùbá Drama. M.A. Project: Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.
United Nations 2015. *Universal Declaration of Human Rights.*